# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 933 LAGOS SATURDAY AUGUST 8—AUGUST 14 1964 KỌBỌ MEJI (2D)


## Ija Pari Abuse Buse!

# Kosoko Oloja Npalemo Lati Joba Ilu Eko

EKO — Lẹhin irohin ti a gbe jade ni Satide si o kọ a nkan miran titun ti nṣẹlẹ lori irohin awọn Ọmọ Ọba ti nwọn fẹ joye ni Iga Idunganran. A gbọ wipe awọn Oloye afọbajẹ ti ri iwe kan pataki gba lọwọ awọn idile Ọba Ẹshinlokun ti o bi Ọmọ Ọba Aminu Kosọkọ, Oloye Aṣhajọn Ọlọja Ereko wipe on ni awọn fẹ mu ni idile awọn f'Ọba tuntun ti nwọn nfẹ yan fun ilu Eko.

A gbọ wipe ni irọlẹ ana ni awọn agbalagba ati awọn oloye lọ pari ija kan ti o wa larin Ologbe Ọba Adele Keji ati Oloye Kosọ ọ ni Ikoyi ninu ile ti Ọmọ Ọba Adetokunbọ Ademọla, Olori awọn adajọ agba gbe ngbe. Nwọn ko gba awa oniwe irohin laye lati joko si ibi ipari ija na ṣugbọn a gbọ wipe wọn tiṣe ọrọ na ni ọrọ ala ọbi, nwọn ti pari rẹ.

A gbọ wipe ija Oloye Kosọkọ nikan kọ ni awọn Oloye Eko pari ni Ikoyi lana, nwọn fẹnu kan ti awọn ijoye yoku ti Ọba Adele ni on yọ wọn loye: awọn na ni Oloye Onilẹgbalẹ, Olorogun, Olumẹgbọn ati Ọbanikoro.

Ọdun keji ti awọn Oloye na ti ye ba Ọba Adele jiroro niyi, nwọn ko si fẹsẹ wọn wọ iga mọ titi ti Ọba na fi waja.

Awọn opitan kan ti nwọn mọ itan diẹ nipa awọn Oloye ilu Eko sọ fun wa wipe idile Shokun kan ko jọba ninu Iga Idunganran ri a fi Iga Onilẹgbalẹ.

## Aseye Ojobi Ogbeni Thompson Dun

EKO — Gbogbo awọn Gbajumọ lọkunrin ati lobirin ni nwọn pesẹ si ibi aṣeyẹ Ọjọbi Ọgbẹni Taju Thompson alakoso iwe irohin Eleti-Ọfẹ ti o ṣe ni jarun ọjọ Ajo ni Idita l'Eko. Irọ ẹ ni aṣeyẹ ọjọbi na ẹrẹ, o si to agogo kan oru ki olukuluku awọn ẹni ti nwọn fi iwe pe sibẹ to gba ile wọn lọ.

ỌLAIYA, afiluṣeoge nibadi pẹlu awọn ọmọlẹhin rẹ ni nwọn sere nibẹ, Ọgbẹni Taju Thompson Ọlọjọbi paapa si fi nkan jije ati ọti mimu tẹ gbogbo awọn to wa sibi ẹyẹ na lọrun.

( Wo yoku loju ewe kẹjọ )

## Adajo Taylor Se Odaran Kan Lore

EKO — Ọrọ kan ti awọn agba ma nsọ pe inu rere ki gbe ni o fara mọ ore kan ti Adajọ Agba Kootu nla Ọgbẹn J.I. Taylor ṣe fun ọdaran kan to wa ni itimọle Teṣan awọn Ọlọpa ni Ebute-Metta ni ọjọ kerin oṣu yi, nigbati o fun ọdaran na ni ẹwu awọtẹlẹ ṣọọti titun meji lati fi gba otutu oworọ si nwọn to ṣe ẹjọ rẹ.

Lọjọ ti adajọ agba na nṣe ayẹwo ile awọn ọlọpa kiri ni o foju kan ọdaran na nibiti o nya otutu, o ni "anu ṣe on pupọ lati ri pe o fi ara rẹ silẹ fun otutu buruku" ti o wa ni asiko yi. Joseph Olujinmi ni ọdaran na niẹ, o si ti wa ni itimọle lọdọ awọn Ọlọpa ni Oyingbo t pẹ ti awọ ko ti fẹnu kan ọrọ rẹ ki adajọ-agba yi to ṣe alabapade rẹ.

(Wo yoku loju ewe keji

## IBOSI OLE L'EKO

EKO — Awọn onijibiti, ole, alọnilọwogba, alọkolohunsigbe, awọn oniwayo ti wọ ilu Eko lati Mushin lati nan bi ijeta ni nwọn ti ngbe apo jibiti kakiri adugbo ilu Eko. Nwọn bẹrẹ lati Popo-Aguda titi de Oke Olowogbowo.

Ti o ba pade awọn, awọn a wọ aṣọ ti o mọ daradara sọrun bi wọn ọmọluwabi akọwe agba ti o nṣe iṣẹ ti o ni lari. Ti nwọn ba wọle tọ ẹ, nwọn a fi orişirişi ogun Oyinbo ti awọn nta han ẹ.

Ẹnu wọn dun pupọ: nwọn a pe ogun oju fun ọ ni ti ori fifọ n wọn a si pe ogun ẹhin ni ti ẹsẹ. Owo ke ere kọ ni nwọn si nda le wọn lori

Boya nwọn le wọ ile rẹ wa, yara le wọn sọnu, ole alafọwọra ni nwọn, maṣe jẹki nwọn lo jibiti fun ọ.

—OLOTU

# Awọn Egbe Imale Raolat Jannat Sere L'Eko

EKO — Irohin ko to afojuba, eni ba debe lo le sọ nị ere aladun kan tị awọn ẹgbẹ Raolat Jannat Islamic Society ṣe ninu Gbọngan ile-ẹgbẹ awọn ọkunrin atị obinrin to wa ni Oko Awo nị Eko ni ọjọ Abamẹta tị aṣe ọjọ kini oṣu yị.

Ajọdun ere ti nwọn ṣe yi jẹ nipa iranti ọjọ Ibi Ojiṣẹ Ọlọrun Anabi Mohammed (ikẹ atị ọla ki o ma ba a). Awọn ti nwọn jẹ Oloye ninu ẹgbẹ na ni awọn Ọgbẹni S. A. Lambo Baba egbẹ, F. A Onibudo, Akọwe ẹgbẹ, Y. K Azeez, Akọwe eto owo ẹgbẹ, L.B Ede Akọwe alabojuto nipa fẹsẹmulẹ ẹgbẹ.

Awọn alaga ọkunrin nibi aṣeyẹ ọjọ na ni A F Badru Adeoro Ipaye S. Arowolo, Alhaji A.H.A. Yusuf, Alhaji Fatoh abo oruko awọn alaga obinrin ni Mujinat Ṣobọwale ati Sabalemọtu Ologundudu, gbogbo awọn ti nwọn wa sibẹ to ọdunrun enia (300).

Ninu ọdun 1957 nị nwọn ti da ẹgbẹ yi silẹ. Tọkuntobinrin wọn nwọn ṣe bẹbẹ lọjọ na pẹlu ọmọ ile kewu Oriṣi mẹta ti oruko wọn njẹ Salawu Deen Arabic Students Oguntoro Arabic Students ati Alfa Giwa Arab Students ni nwọn fi ere ori aladun gbe eyẹ ọjọ na niyị.

Enu ti o koko fi ọrọ iwuri ṣi irọya ọjọ na ni Alhaji Fatoyinbo pẹlu ọrọ gbohungbohun, o si ṣe alaye bi iṣẹ aṣiwaju ṣe ṣoro si lati ṣe o nị nipa bayị o yẹ ki awọn aṣiwaju ẹgbẹ na ni suru kịkun lati wa ma fi ṣiṣẹ wọn.

O tun ba awọn ọmọ ile kewu sọrọ pe ki wọn ṣọra ninu iwa iṣekuṣe larin ọkunrin ati obinrin paapa ninu awọn to jẹ ọmọ ẹgbẹ o tun ṣe adura fun ilọsiwaju ẹgbẹ na.

Lẹhịn eyi ni awọn meji kan ka iwe Kurani ni iranti ọjọ na ohun wọn dun pupọ o wu enia lori. Nigbati nwọn pari rẹ tan nwọn da atẹwọ ati ọrọ iyin bo wọn, eleyi fi agbara a i adun adura ti Afa I.M Salawu ṣe han nigbati o koko si ajọdun na

Ninu ọrọ kan ti alaga ẹgbẹ, Ọgbẹni Fatoyinbo sọ o bẹ gbogbo awọn onimale loruko R J S lati ni igbagbọ ninu ẹsin Imale, ki awọn ẹgbẹ paapa si ni suru ati ifarada ninu iṣẹ wọn, bẹ na si ni wọn igbimọ ẹgbẹ pẹlu

Nigbati awọn ọmọ ile kewu si bẹrẹsi kọrin tị nwọn si njo bi okoto, ori ọpọ enia lọkunrin ati l'obinrin wu tobẹgẹ tị nwọn si nrojo owo le wọn lori.

Pọun mẹdọgbọn ni alaga fun wọn, lẹhinna nị nwọn tun ha awọn oriṣiriṣi onjẹ adidun ati awọn ọti Aladun (Minerals) fun ogunlọgọ awọn ti nwọn wa si ibị ere na.

# Adajo Ni Ki Kongirakito Shodipo San Gbese Orun Re

EKO—Ni ọjọ kejidinlọgbọn oṣu ti o kọja nị kotu ganran l'Eko ni nwọn ṣe idajọ ẹjọ gbese kan ti awọn ile iṣẹ Faranse onịna tị nwọn nfi ẹlẹntirịkị sinu ilo (The Nigerian Electrical Contracting Co. Ltd), fun awọn enia pe ọgbẹnị Harold ṣodipọ ati iṣe ti o dasilẹ, adajọ nị ki kongirakito Shodịpọ lọ san owo tị o jẹ awọn Oyinbo Faranse na fun wọn lọgan.

Ọgbẹni J. A. Adefarasin ti o je adajọ agba to ṣe ẹjọ na ti paṣẹ pe ki ọgbẹni Harold ṣodipọ ni oruko ịle iṣẹ rẹ ẹgbẹrin o din adọta pọun (£750) owo oju gbese pẹlu pọun mejilelọgọji (£42) owo irinsẹ.

Gẹgẹbị ọrọ na ti ri awọn ile iṣẹ alagbaṣe ẹlẹntrịriki na ni awọn adehun pe awọn yịo gba ojile-legberịn o le mẹta pọun ṣile mẹdogun atị kọbọ mẹsan (£943:15, 9d) fun iṣẹ agbaṣe sịso ina elentriki mọ awọn ọja Ebute Ero ti tun ti nwọn ṣeṣẹ kọ, atị ninu eyiti ọgbẹnị Harold Ṣodipọ jẹ ọkan ninu awọn alagbaṣe ọja na larin oṣu kọkanla ọdun 1961 ati oṣu keje ọdun 1962.

Harold Ṣodipọ ti san igba pọun o din pọun meje ṣile mẹdogun ati kọbọ mẹsan pere ni kele ti nwọn ti gbe ẹjọ na wa si kotu, o si ṣe aroye wịpe iye owo to ṣẹku jẹ eyiti awọn alagbaṣe ina ẹlẹntiriki na yio faramọ dipo gbese atị inira ti nwọn fun on nipa aitete parı iṣẹ ti on gbe fun wọn ṣe si asiko to awọn pinnu le lori.

Harold Ṣodipọ tun se alaye pe ninu ịwe adehun to wa larịn awọn mejeji ilana kan wa nịbẹ eyiti o se pe fun ọse kọkan tun fifi ise na falẹ lẹhịn adehun ọjọ ti iṣẹ na yio parị ọgbọn pọun ni awọn alagbase na yịo ma fi rẹra, sugbọn awọn alagbase ịna ẹlẹntırịkị na faake kori jalẹ wịpe iru ilana bẹ ko si ninu ịwe adehun awọn ti awọn jọ fi ọwọ si.

Adajọ ni on ri wịpe Shodipọ paapa ni ko tete pari kịkọ ọja Ebute-Ero na kịsẹ awọn Oyinbo yi.

E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin

**ELETI–OFE**

ti o kun fun irohin aladun losose.



# Awon Olosa Jale Ninu Reluwe Lori Irin

KANO — Ọjọ Abamẹta ti nṣe ọjọ kini oṣu yi ni a gbọ irohin kan lati ilu Kano ni ipinlẹ Ariwa wipe awọn ọlọṣa kan pẹlu ihamọra awọn ohun ọṣẹ bi ibọn ati ada bẹ lu ọkọ Reluwe kan ti o nti Kano lọ si Port Harcourt lori ere, nitosi ibudo reluwe kan ti nwọn npe ni Oadi Station nwọn si ko ẹru awọn ti nwọn w ninu ọkọ.

Irohin kan lati ilu Kano sọ pe awọn ọlọṣa na pẹlu awọn bẹ wọ inu loju ọkọ reluwe lojiji nwọn si bẹrẹ si fi ku ọ lu awọn ero inu rẹ ti ti nwọn ko lati jọwọ ẹru ati owo wọn.

A tun gbọ wipe gbogbo ẹru ti nwọn ko pẹl fifi ibọn deruba tabi ẹbe rin pọun niye owo (£800

Lẹhin ti nwọn ti pari iṣẹ jamba yi tan awọn ọlọṣa na ba fa ẹwọn onirohin kan ti wọn se sinu ile ero lati ma fi da ọkọ duro ti nkan abami tabi lojiji, ba ṣẹlẹ, ọkọ na si duro lojiji gbogbo wọn ba bẹ lu ibo.

# Tiger Abese Ku Bi Ojo

NEW YORK - Ọmọ ilẹ Naigeria ẹlẹṣẹ kan Ọgbẹni Dick Tiger ni a gbọ wipe o bori ẹniti o ba ja ni ọjọ Ẹti (Friday) to kọja yi oruko ẹni ti o ba ja na njẹ Puerto Rican Jose Gonzalez ni ori ẹkẹfa ni ẹmẹwa ti wọn nlọ ni Madison Square Gardens.

Ọmọ ọdun merin lelogoji ti o fi igbakan jẹ olori ẹlẹṣẹ ipo Middleweight fi ẹṣẹ dara fun Ogbẹni Gonzalez ọmọ ọdun merinlelogun na ti o fi jẹ wipe reluwe ni o da ija na duro ligbati Tiger fi ẹṣẹ gbe ọkunrin na lulẹ nipa fifi ẹṣẹ si n ẹnu.

Tiger sọ ni iyara ti o ngbe nmura pe on ko fi ibikan pa rara o na ija na da bi ẹnipe ko ju igba mẹta lọ loju on,

# Eleti-Ofe Daraba

YOUR SPECIALIST FOR ALL
BUILDING MATERIALS
BROSSETTE
(NIGERIA) LTD.
WHARF ROAD - APAPA - (NIGERIA)
P.M.B 1135 - APAPA
At your service
• STOCK
• SPECIAL ORDERS
• TECHNICAL INFORMATIONS



Dick Tiger ati Iyawo Re

Nigbati awọn oniwe irohin nbi lere wipe bawo ni ọjọ iwaju yio tiri npa ẹṣẹ, o sọ fun won wipe ki nwọn o lọ bi oga on ti o ẹ Oyinbo (Manager) Ọgbẹni Bobby Diamond, o sọ wipe yio ran o lọwọ dada.

Ọgbeni Harry Markson ti o pe ija ni si Madison Square Garden sọ wipe on yio sa agbara on lati jẹ ki Tiger ati Archer ja ninu oṣu kẹwa ọdun yi.

# ELETI - OFE

(A NJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMM
38, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 2337

VOL. XIV. NO 933 SATURDAY Aug. 8 — Aug 14 1964


## Oro Olotu:

# Ogun Adaja !

Irohin kan ti a gbọ lati Oke Ọya wa wipe awọn alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa fẹ ṣe iwadi ọrọ owo kan ti awọn Fulani onimalu ni awọn ara Ipinlẹ Ila Orun ngba lori awọn malu awọn ti awọn nda wọlu ati adehun igi ti nwọn nko wọlu ti awọn jọ ṣe ti nwọn fẹ parẹ.

A gbọ wipe minisita kekere kan, Alhaji Rufai ti nṣe ileri wipe bi ọrọ na ba jẹbẹ, Ijọba awọn ni Oke Ọya ni lati gbẹsan lara awọn Ibo. O ni gbogbo gari ati epo ti nwọn nko wọlu wa ni awọn yio daduro, ati pe awọn ko ni jẹki awọn Ibo ri ẹja, ororo ẹpa ati alubọsa jẹ mọ.

Ọrọ na fẹ dabi ogun adaja tabi ifi iya jẹ ara ilu lanidi. Imọran ti a ṣe ba awọn ara ipinlẹ mejeji dasi ọrọ na ni wipe ki nwọn jọ joko ro ọrọ na, ki nwọn ṣe ni inubi inubi, ki o ma le da ija nla silẹ.

Itẹpọ gbogbo ara ilu ni a nwa, ko yẹki a tun ma wa ọta kun ara wa. Akoko yi ni a si sọ wipe a nwa idagbasoke fun ilu. Bi a ba mọ wipe lati ile ni a ti nkeṣọ lọ sode, o yẹki a tun ilu wa ṣe daradara ki a to ma lọ silu ajoji lati ba wọn fọ aṣọ wọn mọ.

Iru orukọ wo ni a lero wipe awọn ara ita yio ma pe wa nigbati a ba se ọbẹ ti a ro amala, ti a ko le fun awọn aladugbo wa jẹ, afi awọn alaroo ti ko ba wa tan rara ni ara wa ya si lati ṣe lore.

Ẹ jọwọ ẹ ba wa fi egun otolo t'ọrọ na ki ma gbogun adaja.


# E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin ELETI—OFE

ti o kun fun irohin aladun losose.


# Iwe Si Olotu

# Iyawo Ko Lati Je Majele Awo, Oko Bere Owo Idana

LỌKỌJA — Ọmọge kan, ẹni ọdun mọkandilogun ti orukọ rẹ njẹ Daisa Nwoko, ti o si tun jẹ olukọ ninu ile iwe kan sọ fun kotu kekere kan ni ipinlẹ ilu Kwara ni Lọkọja laipẹ yi wipe Ọgbẹni Mark Okocha ti nṣe ọkọ on sọpe ki on gbe majele awo imulẹ kan jẹ lori pe on ko ni tu adehun ife ti o wa larin awọn mejeji.

Akoko ọrọ yi ni igbati ọmọge Nwokolo njẹri fun ara rẹ ninu ẹjọ itu ifẹ kan ti Ọgbẹni Okocha gbe wa siwaju kotu na, ati lori eyiti o nfẹ gba pọun mẹrindinladọrun ati ṣile meji gẹgẹbi owo idana to san lori iyawo rẹ. Ọmọge Nwokoko tun ni gẹgẹbi agbara ti majele na ni, o ni o lagbara lati le pa on tabi mu ki on ya ọrọ bi on ba le ye adehun owo imulẹ na nitoripe nkan miran bi ija le ṣẹlẹ larin awọn mejeji! bi ọkọ ati aya to si tun le mu ki on wa ọna lati kọ ọkọ on silẹ, nitorina ni on ṣe fi faake kọri lati tete tẹle iru iru imọran wọnyi.

Nigbati ọrọ ti ọkọ iyawo sọ, o sọfun kotu pe niwọn igba to ti jẹ pe iyawo on ti kọ lati wọ awo imulẹ na pẹlu on, ko tun si ohun miran ti on le ṣe le lori fun idana. Ẹ o tun ma gbọ nipa ọrọ na.

# Awon Kan Fi Adamodi Ile Ise Boju Lati Jale

IBADAN — Ni opin ọsẹ to kọja ni irohin kan de si ile iṣẹ wa lati ilu Ibadan pe kotu ganran nla kan ti o wa ni Ibadan ti bẹrẹ gbigbọ ẹjọ kan ti awọn ọlọpa mba awọn enia mẹta ṣe lori ẹsun wipe nwọn ṣe apamọpamọ pọ, ati lati gba awọn eru ọja pẹlu ẹtan, awọn mẹta na ni Sunday Okoro, ẹni ti o npolowo ọja Linus Ezoma ati Ambrose Ewulluh, akọwe olutọju eru ọja to nṣiṣẹ ni ile iṣẹ kan ti nṣe inaturẹsi onirọba ni Ibadan (Nigeria Rubber Company Limited).

Gẹgẹbi alaye ti awọn ọlọpa ṣe nwọn ni ninu oṣu kẹta ọdun to kọja ni awọn ọdaran mẹtẹta wọnyi ṣapamọpamọ lati lu ile iṣẹ onimatarasi na ni jibiti nipa fifi iwe apaiutu kan gba ẹru lati ọwọ wọn ni oruko ile iṣẹ ti njẹ Nigeria Industry Company Limited eyiti ko tilẹ si ohun to jọ rara.

Awọn ọlọpa sọ siwaju si pẹlu ero lati lu jibiti, awọn enia mẹta na gba ọtalerugba o din mẹwa (250) timutimu onirọba ati matirẹsi mẹrin eyiti iye owo wọn jẹ ojilelẹgbẹrin mejila (£741 12s) Ẹleri kan ti awọn ọlọpa pe Alhaji Akintọla Odutọla to jẹ olotu ile iṣẹ na sọ fun adajọ pe on ri iwe iraja awon meji gba loruko ile iṣẹ adamọdi na, on ba pe ṣe fun akọwe ọja Ọgbẹni Ewulluh lati fi eru ti awọn bere na ranṣẹ si awọn ni Port Harcourt

Alhaji Odutọla tun ni lẹ hin ọjọ die on wa ri iwe ingba eru kan gba gẹgẹbi ẹri pe awọn ti eru na gba ati pe nigbati on ko ri owo awọn eru na gbe na akoko ti on nireti si on na (Wo yoku loju ewe karun)

# Nwon Fe Da Egbe-run Osise Duro Ni Ilu Kano

KANO—Ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu keje ọdun yi ni irohin kan ti ilu Kano wa ni ipinlẹ iha Ariwa pe awọn afẹnnişọ ti nwọn jẹ alaşe ile iṣẹ kan nibiti nwọn gbe nkun aṣọ n bẹ ranri pe dandan ni ile iṣẹ na ti nwọn fi adọta ọk pọun kọ (£1,000000) nilati di ti i pa bamu bamu bi ijọba kan ba le mu awọn nipa lati şan owo ọya ẹkunwo eyiti Adajọ Morgan ma şe fun gbogbo oşişẹ awọn gbogbo ipapọ awọn oşişẹ wọnyi le ni ẹgbẹ rẹ.

Ni opin ọse ito kọja awọn mẹtalelọgbọn ni nwọn ti kọkọ da duro lẹnu iṣe şugbọn ninu ọrọ kan ti alage ile iṣẹ na, ọgbẹni Abou Lafia mba oniwe irohin kan sọ o ni ohun ti o mu awọn alaşe ile iṣe na lati şe bẹ ni nitoripe awọn ti nwọn da duro yẹn fẹrẹ da ogun silẹ nibişẹ ni ọsẹ to kọja.

O tun sọpe gbogbo awọn oşişẹ na ni nwọn mbẹ soke bẹ sodo ninu ọgba ile ise na ni ọsẹ to kọja nwọn kọ lati şişẹ nitori fifi aake kọri lati san ẹkunwo na fun wọn.

Alaga na tun fi yeni pe nigbati on bẹ awọn oşişẹ na lori ainipa ile ise na lati san owo yi ẹpọlọpọ gba lati gba ọrọ ti on sọ nwọn si mura lati pada sẹnu iṣẹ wọn.

Ọgbẹni Lafia ni awọn olori ẹgbẹ buburu ninu awọn oşişẹ na ni nwọn mu ki awọn to ku gbinaya ti nwọn si bẹrẹsi ju ẹkufọ igo okuta ati awọn ohun ipanilara lu ile iṣe na

O ni şiwaju rogbodiyan yi awọn alaşẹ ile ise na ti şe eto lati fi sisi (6d) kun owo oşu ẹnikọkan wọn

Ẹdikan to ngbe ẹnu sọ fun awọn ti nwọn ti da duro ọgbẹni Bello Akatu sọfun oniwe irohin po ijọ ngbọn ti awọn oşişẹ na da silẹ ni o fa idaduro wọn lẹnu iṣẹ.

# Ogunlogo Ọmo Egbe UMBC Ni Nwon Ti Wewon

GBOKO— Ninu ọrọ kan ti Ọgbẹni J. M. Yakubu ẹni ti nşe aşiwaju ẹgbẹ UMBC to faramọ ẹgbẹ Ọlọpẹ, ni agbegbe ilu Bẹnue sọ ni ilu Gboko laipẹ yi, o nfi yẹ ni wipe ẹdẹgbarun (9,000) enia ninu ọmọ ẹgbẹ on ni enia ninu ọmọ ẹgbẹ on ni nwọn jiya lọwọlọwọ ninu ọgba awọn ẹlẹwọn jake jado ilẹ iha Ariwa Nigeria.

O fi ọrọ ẹbẹ sọwọ si Olotu Ijoba Apapọ Nigiria Ọlọla Abubakare Tafawa Balewa pe ki o şe eto lati le da gbogbo awọn oşelu ti nwọn ti sọ sẹwọn nitori ọrọ ilu şişe.

Ọgbẹni Yakubu tun ni Olotu Ijọba Apapọ pẹlu olori agba fun awọn ọlọpa ọgbẹni Louis Edet nilati lo ida wọn lati da awọn ọlọpa lẹ un ati ma şişẹ ni ipinlẹ ilu awọn Şọşọ nitori pipa ika ti nwọn nfi ibọn pa awọn ẹniẹlẹni ti ko mọ nkankan.

Siwaju si, o ni o jẹ ẹdun ọ an fun on nipa ipo ihamọ ti marun ninu awọn ọmọ ẹgbẹ on ti nwọn si jẹ aşiwaju ninu ẹgbẹ on wa, awọn ẹniti nwọn fi sun pe uwọn jẹ igi lẹhin fun ija buruku ni ipinlẹ ilu awọn Şọşọ.

# Adamodi Ile Ise

(O bẹrẹ loju ewe kẹrin)

pọun o le kan, ati şile ba gbera lọ si Port-Harcourt lati wadi awọn nkan wọnyi funrara on.

O ni lẹhin ti on ti şe wahala titi lati wa ile iṣẹ na kan, o ba lọ si ile iṣẹ ijọba kan nibiti nwọn gbe rẹjista orukọ awọn ile iṣẹ onişowo ni ilu Port Harcourt (Ministry of Commerce and Industry) boya orukọ ile iṣẹ bẹ wa tabi kosi Alhaji Odutọla ni "Okoro sọfun mi pe ko si ile iṣẹ ti nwọn jẹ orukọ bẹ ati pe on ti ta awọn ẹru ọja na owo eyiti on yio si da san pada fun ile iṣẹ ibiti on gbe nşişẹ. Awọn ọlọpa şi mba ọrọ na lọ.

# Eleti-Ofe Daraba

CARSON PAINTS AND VANISHES









SOLD AGENTS IKORODU TRADING COMPANY
20, & 28, Balogun Street Lagos.

# Awọn Obinrin Ilu Hausa Fe Pe Sardauna Lejo Lori Idibo

ZARIA—Obinrin kan to jẹ aṣiwaju ẹka ẹgbẹ kan ti wọn npe ni "Ẹgbẹ Agbẹp rapọ ati awọn osiṣẹ" ti obinrin ni ilẹ Naijiria ti orukọ rẹ njẹ Malama Ladi ni ilu Zaria ni a gbọ pe o ti pinnu lati pe Olotu Ijọba Ipinlẹ Ariwa lejọ ọlọla Ahmadu Bello ati ijọba rẹ si ile ẹjọ kan fun orkunkun rẹ lati fun awọn obinrin ipinlẹ Ariwa Naijiria ni ominira ara wọn.

Ninu rohin kan to jade ni ilu Zaria n ọjọ Bọ to koja Malama Ladi fi han pe gẹgẹbi eto ofin iṣẹ n fun i ẹ Naijiria, o ti fi h a gbangba pe o to fun ọ ọ'a Ahmadu Bello ati Ijọba rẹ lati mọ pe ki iṣe ohun to boju mu fun wọn fi ẹ t awọn obinrin du w ọ n ni ẹkun rẹrẹ.

Siwaju si o tun ni bi o ba ṣe pe nwọn kuna lati mọ eyi "Awa yio figagbaga pẹlu wọn" O ni eyi ni ẹtoripe bi agbajọ awọn enia ti nwọn w a ni i l o Ariwa (Ni u eyiti awọn obinrin wa) ti p ọ to ni ijọba Apapọ se fi pese awọn ohun anfani fun wọn ju awọn ilu miran l'oku lọ o si wa ya on lẹnu lati ri pe nwọn ni i k o r i r a si awọn obinrin nigbati o ba di akoko ti nwọn ba fẹ lo ẹtọ wọn yatọ si bi nwọn ti nṣe ni ipinlẹ miran.

Malama Ladi ni "Ọlọla Ahmadu Bello ati i j ọ b a adaṣe ẹ n lati mu ọrọ yi dani gẹgẹbi ẹ b ẹ igbẹhin awọn obinrin si wọn la i fun awọn ni ibere awọn."

O tun sọ ọ r ọ iṣiniletì kan pe idibo sinu ile igbimọ ijọba Apapọ to mbọ jẹ ohun pataki si a w ọ n ti nwọn j obinrin ni ipinlẹ Ariwa ati pe awọn ti nwọn jẹ obinrin papa fẹ lati lọwọ ninu ibo didi na.

Malama Ladi ṣeleri fun ọlọla Ahmadu B e l l o pe awọn obinrin yio d a r a agbyanu kan ni akoko ibo to mbọ bi nwọn ba g b a awọn laye, ni ipar o bẹ gbogbo awọn obinrin ni ile Naijiria lati kọ baruwa tele awọn ki nwọn b a l e gba wọn kuro l'oko ẹru ijọba ẹgbẹ Olomi."

---

Fun ina dídá ati fun imọle

BP SUPERLITE KEROSINE

L'ayo!




Ti o ba ṣepe Kerosine lo fẹ BP Superlite l'ayo o le ri rà nibikibi, ko si wọn, o mó daradara, owun lo si dara ju fun onjẹ-sise, ina-titàn ati lati mã fi yãná Kerosine ti oti dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!

BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

# Sardauna Ni Awọn Egbe Alakuko Ko Ladeun

JOS — Bi ebiti ko ba peku, a fẹyin fun ẹlẹyin ni irohin kan ti a gbọ nipa ọrọ kan ti Aṣiwaju Ẹgbẹ Olomi ati Olotu ipinlẹ Ariwa Nigeria, Ọlọla Ahmed Bello sọ ni ilu Jos ni ọjọ kọkandinlọgbọ oṣu keje ọdun yi wipe ẹgbẹ on ko ni si ninu ajọṣepọ mọ pẹlu ẹgbẹ Alakukọ lẹhin eyi.i awọn jọ nṣe lọwọlọwọ, iba ṣe pe ẹ g b ẹ on bori tabi padanu ninu ibo sinu ijọba apapọṣe to mbọ.

O tun nfi yeni pe "Papa bi ẹgbẹ on tilẹ kuna lati ni ọpọlọpọ enia ninu ibo to mbọ, dajudaju ẹgbẹ on ko tun ni wa ninu adehun ajọṣepọ kan mọ pẹlu ẹgbẹ Alakukọ"

Bayi ni Olotu ipinlẹ Ariwa na sọ nigbati o nfi ede Hausa b a Ogulọgọ awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ sọrọ nigbati nwọn nfi ere ijo ibilẹ damuso f u n ni gbangba ile rẹ to wa ni adugbo Tudun Wada ni ilu Jos ninu ọjọ nla kan to rọ lọjọ na.

Ọlọla Ahamadu B e l l o tun ni ki gbogbo awọn enia ipinlẹ Ariwa ri gbogbo ede aiyede bọlẹ ki nwọn si parapọ di ẹgbẹ ọmọ-ogun kanṣoṣo lati takojamba ki amba awọn Ibo "Yanmirin"

Siwaju si, o ni "Ọ r ẹ awọn ni Ibo ti jẹ ri, ṣuawọn ko le d ara kanna" o si tun wa fi owe sọ pe a ọṣe wa pelu wọn ṣe nkan ti o mu iyemeji dani.

Nigbana ni Ọlọla Ahmadu Bello wa ṣe apejuwe awọn Ibo bi awọn ẹgbẹ orilẹ ede kan ti nwọn dara pọ wa ni ilẹ Nigeria ati pe didara pọ wọn bi orilẹ ede kanṣoṣo lọtọ ni o mu ainilọsiwaju ilu ba ilu.

Nitorina, o bẹ gbogbo ọmọ ilẹ Ariwa lati ro nkan wo lẹmeji ki nwọn to ṣe, ki nwọn si gbagbe gbogbo ede aiyede, ki wọn si sowọ pọ lati jẹ ọ m ọ-ogun kanṣoṣo ni atako iwa awọn Ibo ati lati fi opin si ikorira si orilẹ ede ni ilẹ Nigeria patapata.

Lori eyi, Ọlọla Ahmadu Bello gbe iṣẹ nla kan le ori oni alukuu ọmọ ibilẹ ilẹ Ariwa nipa riri wipe kosi ọkan ninn awọn ibudo ibo didi ni ilẹ Ariwa ṣubu sọwọ awọn oṣelu ilẹ Gusu ninu ibo apapọ di to mbọ.

Ni opin ere ijo ibilẹ ti nwọn ṣe fun, Ọlọla Ahmad Bello fi igba o le mẹwa ponun (£210) ni takada owo ta awọn onijona lọrẹ. Lẹhina ni o wa gba ọ n a ilẹ lọ lati ilu Jos si ilu Zaria lati ibiti on yio tun kọja si Kaduna.

# BBC Man At No. 10 Dowing Street

Douglas Brown interviews milkman Jim Locke, who has been delvering milk to 10 DOWING STREET since 1946, for the programme dealing with the official residenca of Britain's Prime Ministeas in the cnrrent BBC General Overseas Service series, 'Sights and Sounds of London'.



10DOWING STREET London, is one of the most famous addresses in the the world. It has been the official residence of Britain's Prime Ministers since the time of Robert Walpole in the early 1 th century. In its function as the Primier's office as wel as his home NO 10 has been the scene of momentous and dramatic events.

Douglas Brown will presnet a picture of Dowing Street through the eyes of people who have worked there. Vistors to London are often struck by the unpretentious frontage of No. 10, situated in a modest street off Wetehall. The original house, built by Sir George Dowing at the end of the 17th century, was later linked at the rear, to another, much larger houre, overlooking Horse Guards Parade. NO 10, and the nieghbouring Nos. 11 and 12 Dowing Street, recently underwent extensive reconstruction. and the architect-in-charge, Mr. Raymond Erith, will be interviewed in the programme. Others taking part include Lord Francis-Williams, Puplic Relations Adviser to former Prime Minister Mr Clement Attlee, and Sir Harold Evans, for many years Press Adoiser to Sir Anthony Eden and Mr. Harold Micmillan when they lived at No. 10.

---

**Plushes, Velvets, Velveteen, Damasks & Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street, (Faji Market)

LAGOS NIGERIA,

The House where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed.

## British Parliament Adjourned

LONDON—The British Parliament adjourned at the weekend for the summer recess until Monday, October 19 although the work of the last session at this stage is not finally over:

Excluding unforeseen emergencies, however, today's adjourmeot would seem in effect to mark the end of the present Parliament. A general election is to be held in the autumn, and unless something quite unforeseen emerges M. P. S are likely only to reassemble in this final session for the formal business of prorogation.

## "Best Student' Award At British Hospital

LONDON—Mr Alfred Nzekwe of Abagana, has just been adjudged the best male student nurse of the year at [illegible] Hospital, Wells, in the West of England.

Mr. Nzekwe has been at the hospital since October, 1961 and is nearing the end of his training which he hopes will earn him a certificate as a Registered [illegible] Nurse in two months' time.

"When I have got that," he told [illegible] P. S correspondent, "I shall take a further course in hospital administration as I feel that I shall be of more value to my country if I know something about this as well"

---

**Read and Advertise in ELETI-OFE your weekly most exciting Yoruba Newspaper.**

---



# Adajo Se Odara Kan Loore

(O bẹrẹ loju ewe k ẹni )]

Joseph O uj mi pẹlu awọn ọdaran mẹdogun mịran ni awọn ọlọpa ko si ịtimọle kotu kekere to wa ni Ebute-Metta fun ịdajọ lori orişirişi ẹsun ti nwọn mu wọn fun

Nigbati Ọgbẹnị Taylor lọ şe ịbẹwo le itịmọle awọn ọdaran wọnyi, ibanujẹ ọkan nị o ję fun lati rị iru ịpo egbin ti ile na wa. O nị "O dọtị pupọ ju" O dọti pupo ju" "Ọmọ eo a ni awọn wọnyị jẹ, ko si jẹ ohun to boju mu lati fi wọn pamọ sinu ile ẹgbịn bayị tị ko tilẹ dara to fun ẹlẹdẹ lati gbe inu rẹ"

Olujimị nị ẹnitị o kọkọ kesi adajọ Taylor nịgbati o nduro de akọwe agba kotu kekere na o si sọ pe "Jọwọ ẹ ma şalaị gbọ aroye mị yi, Ọgbẹnị"

Nịgbawa ni Olujịmị wa şe aroye pe on ti wa ninu ịtịmọle lati oşu keji ọdun yi. "şugbọn awọn ọlọpa nfi ẹjọ on fale lati igbana Aroye yi ni o rọ şe lọwọ nigbati ipo f fẹrẹ wiwa ni ihoho ti Olujịmị wa şe kongẹ akiyesị adajọ agba na, o si bere pe "Kinişe ti o ko wọ aşọ sara rẹ ?"

o sị dahun pe "aşọ awọleke kanşoşo ti mo nị ti gbo tan nigbogbo igba ti mo tị wa ni itimọle"

Warawere adajọ na tị ni ki derẹba mọto rẹ mu ẹwu meji wa fun lati ịle, o ni ẹnikan ni o şa bi ii .

# Olopa Fo Iho Awon Ogboju Ole

OWERRI—Laipẹ yi ni a gbọ pe awọn ọlọpa Naịjirịa ni ilu Owerrị nị ipịnlẹ Ila Orun ti gbogun tị ọkan nịnu awọn ẹgbẹ ọlọsa ti nwọn tị nda ọpọlọpọ awọn ara ịlu Isamu kakiri ipinlẹ Ila Orun, nwọn si ti mu mẹfa ninu awọn ọmọ ẹgbẹ wọn ti nwọn jẹ ịgi ịẹhịn ọgba fun awọn

Awọn ọlọpa nị laipẹ yi ni awọn ọlọsa wọn yi gbogun ti wọn ni agbegbe ilu Owerri ni ọjọ kẹdọgbọn oşu to kọja ati nị ileto kan ti nwọn npe ni Akobo nibiti nwọn gbe doju ija kọ ọgbẹni Emmanuel ure-pẹlu ibọn.

Nwọn ni ni oru ọjọ kan na nwọn tun gbogun ti ẹnikan to jẹ alaga Kansulu Ilu Ikeduru şugbọn ọpọlọpọ awọn ọta ti nwọn yi sịi ko ba.

A tun gbọ pe ni opin oru ọjọ kanna nwọn fi ịja pẹ ẹta pẹlu aluta şọşi kan ti o ngbe ilu Ulakwo.

Mimu awọn aşiwaju ẹgbẹ ọlọsa ti nwọn lọwọ si ole jịja wọnyi, ti ẹjọ won sị wa nị Lotu lọwọlọwọ je eyiti o ,fara mọ isowọpọ şişẹ awọn ọlọpa inu to wa ni ịpinlẹ ilu na.

## Aseye Ojobi

( O bẹrẹ loju ewe kinni )

Awọn dẹ ti aye wa lati daruko ninu awọn tị nwọn wa sibị oseye ọjọbi na, Awọn Oloye M. A. Ogun Wahab Balogun, Faramọ bị Ajadi Akerele. Wusu, Alhaji Lad Agoro Alhaji M. A Tijani Alhaji A.R Amusa, Alhaji R saki Alọ bọ Alhaji S. S. Fashọla, Alhaji Mogaji.

A ọ Ọgbẹni A F Odulele, Alex ..., O Idewu, B R ...su, Br ...o, OB Adedoyin, Ola Oshitade, Oloye F g e o Be ..., M. A. Thompson, G wa Osagie, W dd l Thompson.

Iya Afin Nasiru Sidi Thompson Sidi S muel, Saki Samuel, a e Ẹlẹ mẹrọ M l ... n gbanjo ati Juliet Thompson.


AFRICAN SPECIAL

* Full tropicalisation and underbody protection plates
* Strong and comfortable suspension.
* Outstanding road holding.
* Modern workshops and spare parts stores, manned by Factory Trained Staff.
* HIGH RESALE VALUE.

DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA, & EBUTE METTA, IBADAN KADUNA, KANO JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT HARCOURT & ABA.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos Phone 23310, Editor, (Olotu) Ọla Ọnatade 15, Kosọkọ Street, Lagos, P O 467, Lagos.